OWE

A ki i t'oju egun w'efọn

# Irohin Yoruba

VOL X No. 432 MONDAY JULY 26, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba

# OBA AKARIGBO FI AWON ARA OFFIN JE OYE, IJA PARI

**ṢAGAMU -- Ni aipẹ yi ni awọn Ọlọla ati awọn enia pataki-pataki wa ṣe atunṣe edeaiyede ti o ti wa larin awọn ara Adugbo Ọffin ni Ṣagamu ati Ọba Alaiyeluwa Awolesi, Erinwọle Keji Akarigbo Ijẹbu-Rẹmọ.**

Ohun ti o ti fa edeaiyede na ni ti Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin, ti o ti fi igba kan du oye Ọba Akarigbo lati jẹ ti ko si bọsi fun un ni awọn enia wọnyi ti o jẹ alatilẹhin fun Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin ba taku lati lọ sujada f'Ọba lati igbana.

Ṣugbọn nisisiyi ti Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin ti di ọrẹ Ọba na ni awọn alatilẹhin rẹ ba gba lati f'aramọ Ọba Akarigbo titun na. Awọn enia mẹfa ti Ọmọ-Ọba Adeleke Adedoyin ti fi jẹ oye ni Ọba Akarigbo na parọ oye wọn nṣe ti awọn pari ija yi tan ti o si fi onikaluku wọn jẹ oye ti o tọ si i.

Diẹ ninu awọn alatunṣe na ni Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ Alakoso Ijọba Iwọ-Orun, Ọba Odẹmọ Ishara, Ọba Ẹwusi Makun, Oloye Okupẹ ati ọpọlọpọ awọn enia pataki-pataki ti ko si aye fun lati da orukọ wọn.



Ọkan ninu awọn ara Offin ti Ọba Akarigbo fi joye ni o kunlẹ siwaju Ọba na ninu aworan yi.

## Ọmọ Imọpo Ṣe Ipade Pataki

OYAN-- Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ keji oṣu yi ni gbogbo awọn ọmọ Imọpo ti o wa ni gbogbo ilu agbegbe Ọyan pesẹ si ilu Ijabẹ fun ipade pataki lori ilọsiwaju awọn ọmọ Imọpo. Ipade na bẹrẹ ni nkan agogo mọkanla owurọ, nwọn si da ọpọlọpọ imọran ti o le mu ilọsiwaju ati irẹpọ wa larin awọn ọmọ Imọpo.

Nwọn tun ta ara wọn ji lori bi o ti tọ ti o si yẹ pe ki awọn ma a wa ni ifọwọ-sọ'-wọ-pọ fun gbogbo ohun rere ti o ba kan ẹnikẹni ninu awọn lati ba a ṣe, ati pe bi inira ba si de ba ẹnikẹni ninu wọn ki awọn duro ti i lati yọ ọ ninu rẹ, nwọn pari ipade na ni nkan agogo meji ọsan.

Lẹhin na ni nwọn gba adura, nwọn si jẹ orisirisi onjẹ adidun, nwọn si mu ọpọlọpọ ọti ati siga. Ipa-

Wo oju ewe kẹtin

## Shittu Adefẹmi Ko Ọmọ Meji Jade

OYOKO - EFFIDUASI ASHANTI G.C. Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu kẹrin ọdun yi ni awọn Iyawo Shittu Adefẹmi (Ọmọ Inisha) mejeji Asiawu Irinoye ati Rabi Ọmọṣọlape bi ọmọ-binrin ni ọjọ kanna.

Ni ọjọ kejọ ni nwọn ṣe ikomọ awọn ọmọ-binrin mejeji na, Alfa Raji Perlẹpẹ Anobi ni o ṣe isẹ ikọmọloruko na, orukọ awọn ọmọ na ni Sinbiatu Abiade ati Mulikatu Faramade. Ikomọ na dun o larintin, baba awọn ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn ti o wa sibẹ lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni Joseph Ajiṣafẹ (Alaga), Bakare Ayanleke, Oailu), Amusa Adeyẹmi (Onijọ), ati awọn Ọgbẹni Bello Adebọjẹ, Shittu Ayanda, Bakare Ọmọkanye, Sunmọnu Ọyalaje, Rufus B. Tẹlla, awọn Iyaafin Ṣifawu Subuloye, Awawu Ayọka, Rafatu Oyelọla ati Aṣawu Agbẹkẹ.

Ki Olọrun da awọn ọmọ na si ki O si fi ire ka ti o

## Akinboye Ku Iku Ojiji

EKO-Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni Ọgbẹni Oyeleke Akinboye, ọkan ninu awọn oṣiṣẹ Amalgamated Press of Nigeria Ltd., Lagos ti o ngba irohin kakiri ita fun "Daily Service" ṣe agbako iku-moto.

Ni alẹ ọjọ na ni awọn ọmọ ilu rẹ, Awọn "Awẹ Education Committe" nṣe ere aladun kan ni Gbọngan Apejọ Glover l'Ebutẹ Metta lati fi ko owo jọ fun ẹkọ, o lọ sibẹ lati woran bi o si ti jade si'ta ni moto kan ba sure kọlu u ti o si pa a lẹsẹkẹsẹ.

Ni ọjọ keji ni nwọn lọ sin oku rẹ si ilẹ Ikoyi, Alufa E. A. Atilade ni o ṣe isin isinku rẹ. O fi iyawo rẹ silẹ pẹlu oyun. Ki Oluwa fi ẹrun kẹ ẹ, ki O si tu iyawo rẹ pẹlu awọn ẹbi rẹ ninu.

## LAKAYE ỌRỌ

Ti a ba wa ni alafia ki a maṣe tu ara ija silẹ, toripe gbogbo ero ọta, ogun ni lojojumọ. Ti a ba si wa ninu ogun, bi alafia yio ti ṣe de ni ijakadi ti a ni lati ma a ja. Agbalagba ti ko ba tu ara ija silẹ nigbakan, ọmọde ko le ri i fin. Igbesi aiye ẹda ogun ni.

## Ọkunrin Kan Bẹ S'Omi Lati Ori Gada Iddo

EKO-Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni awọn Olọpa mu ọmọkunrin kan wa ba ṣe ẹjọ ni Kotu Kekere pe o fẹ pa ara rẹ si Ijọba l'ọrun nitoripe o bẹ lati ori gada Iddo (Lagos Carter Bridge) sinu odo ọsa.

Ọmọ-kunrin na njẹ David Alabi, o wọ akisa ṣokoto penpe kan ti o dọti.

Nigbati awọn Ọlọpa gbe sinu apoti lati ro ti ẹnu rẹ, bi o konran ki o sọrọ nṣe ni o nfi ọwọ ṣe apejuwe bi odi. Apejuwe rẹ na ko si ye ẹnikẹni.

Ni Adajọ ba pe ki nwọn mu u lọ si ọdọ Dọkita lati yẹ ẹ wo, nigbati Dokita yẹ ẹ wo tan, o ni inkankan ko ṣe e, o adibọn ni, ni Adajọ ba fi ẹjọ rẹ si igbamiran.

Western Regional Production Development Board

WRPDB

## Printing Engineering Scholarship

In addition to the courses already published in the advertisement for Western Regional Production Development scholarships, the Board is also prepared to make further awards in

PRINTING ENGINEERING

Applicants must be of Western origin.

The minimum qualification required is Cambridge School Certificate Grade I. Preference will be given to applicants already in the Printing Trade.

Application Forms can be obtained from the Secretary, Scholarship Branch, Western Regional Production Development Board, Secretariat, Ibadan.

Application Forms must be returned to the Secretary through applicants' Heads of Departments or Firms to reach the Secretary not later than 31st July, 1954.

SECRETARY,
Western Regional Production Development Board.

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY --- GET REDIFF-SION

